WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com

| |
|---|
| P3291 Nov.<br>WASSCE 2007<br>YORÙBÁ 1<br>Objective Test<br>1 hour<br>**1** |

Name:.............................................................

Index Number:.....................................................

# THE WEST AFRICAN EXAMINATIONS COUNCIL

## West African Senior School Certificate Examination

YORÙBÁ 1

November 2007 OBJECTIVE TEST 1 hour

[ 60 marks ]

*Do* **not** *open this booklet until you are told to do so. While you are waiting, write your* **name** *and* **index number** *in the spaces provided at the right-hand corner of this booklet and thereafter, read the following instructions carefully.*

1. Use **HB pencil** throughout.
2. If you have got a blank answer sheet, complete its top section as follows.
   *(a)* In the space marked *Name*, write in capital letters your **surname** followed by your **other names.**
   *(b)* In the spaces marked *Examination, Year, Subject* and *Paper*, write **'WASSCE', '2007 Nov.', 'YORÙBÁ'** and **'1'**, respectively.
   *(c)* In the box marked *Index Number*, write your **index number** vertically in the spaces on the left-hand side. There are numbered spaces in line with each digit. Shade carefully the space with the same number as each digit.
   *(d)* In the box marked *Paper Code*, write the digits **329112** in the spaces on the left-hand side. Shade the corresponding numbered spaces in the same way as for your index number.
   *(e)* In the box marked *Sex*, shade the space marked **M** if you are **male**, or **F** if you are **female.**
3. If you have got a pre-printed answer sheet, check that the details are correctly printed, as described in **2** above. In the boxes marked *Index Number, Paper Code* and *Sex*, **reshade** each of the shaded spaces.
4. An example is given below. This is for a **male** candidate, whose **name** is **Chukwuma Adekunle CIROMA**, whose **index number** is **5251102068**, and who is offering **Yorùbá 1**.

**THE WEST AFRICAN EXAMINATIONS COUNCIL**

PRINT IN BLOCK LETTERS

Name: CIROMA (Surname) CHUKWUMA ADEKUNLE (Other Names) Examination: WASSCE Year: 2007 NOV.

Subject: YORÙBÁ Paper: 1

| INDEX NUMBER | |
|---|---|
| 5 | c0⊐ c1⊐ c2⊐ c3⊐ c4⊐ ■ c6⊐ c7⊐ c8⊐ c9⊐ |
| 2 | c0⊐ c1⊐ ■ c3⊐ c4⊐ c5⊐ c6⊐ c7⊐ c8⊐ c9⊐ |
| 5 | c0⊐ c1⊐ c2⊐ c3⊐ c4⊐ ■ c6⊐ c7⊐ c8⊐ c9⊐ |
| 1 | c0⊐ ■ c2⊐ c3⊐ c4⊐ c5⊐ c6⊐ c7⊐ c8⊐ c9⊐ |
| 1 | c0⊐ ■ c2⊐ c3⊐ c4⊐ c5⊐ c6⊐ c7⊐ c8⊐ c9⊐ |
| 0 | ■ c1⊐ c2⊐ c3⊐ c4⊐ c5⊐ c6⊐ c7⊐ c8⊐ c9⊐ |
| 2 | c0⊐ c1⊐ ■ c3⊐ c4⊐ c5⊐ c6⊐ c7⊐ c8⊐ c9⊐ |
| 0 | ■ c1⊐ c2⊐ c3⊐ c4⊐ c5⊐ c6⊐ c7⊐ c8⊐ c9⊐ |
| 6 | c0⊐ c1⊐ c2⊐ c3⊐ c4⊐ c5⊐ ■ c7⊐ c8⊐ c9⊐ |
| 8 | c0⊐ c1⊐ c2⊐ c3⊐ c4⊐ c5⊐ c6⊐ c7⊐ ■ c9⊐ |

| PAPER CODE | |
|---|---|
| 3 | c0⊐ c1⊐ c2⊐ ■ c4⊐ c5⊐ c6⊐ c7⊐ c8⊐ c9⊐ |
| 2 | c0⊐ c1⊐ ■ c3⊐ c4⊐ c5⊐ c6⊐ c7⊐ c8⊐ c9⊐ |
| 9 | c0⊐ c1⊐ c2⊐ c3⊐ c4⊐ c5⊐ c6⊐ c7⊐ c8⊐ ■ |
| 1 | c0⊐ ■ c2⊐ c3⊐ c4⊐ c5⊐ c6⊐ c7⊐ c8⊐ c9⊐ |
| 1 | c0⊐ ■ c2⊐ c3⊐ c4⊐ c5⊐ c6⊐ c7⊐ c8⊐ c9⊐ |
| 2 | c0⊐ c1⊐ ■ c3⊐ c4⊐ c5⊐ c6⊐ c7⊐ c8⊐ c9⊐ |

**SEX**

Indicate your sex by shading the space marked M (for Male) or F (for Female) in this box: M ■ F ☐

For Supervisors only.
If candidate is absent shade this space: ☐

INSTRUCTIONS TO CANDIDATES
1. Use grade **HB pencil** throughout.
2. Answer each question by choosing one letter and shading it like this: [ A ] [ B ] [ C ] ■
3. Erase completely any answers you wish to change.
4. Leave extra spaces blank if the answer spaces provided are more than you need.
5. Do not make any markings across the heavy black marks at the right-hand edge of your answer sheet.



© 2007 *The West African Examinations Council*

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com


## PÉPÀ 1
## ÌBÉÈRÈ ÈWONÌDÁHÙN

*Dáhùn* **gbogbo ìbéèrè** *tí ó wà nínú pépà yìí.*

*Ka àwọn ìbéèrè yìí dáradára kí o sì mú ìdáhùn tí ó tọ̀nà fún ìbéèrè kọ̀ọ̀kan nínú àwọn tí a pèsè ní* A – D. *Kun àlàfo tí ó wà níwájú lẹ́tà tí o mú ìdáhùn rẹ̀ sínú ìwé ìdáhùn tí a pèsè fún ọ.* **Pẹ́ńsù** *ni kí o lò láti kun àlàfo tó bá ìdáhùn rẹ mu. Bí o bá fẹ́ yí ìdáhùn rẹ padà, rí i dájú pé o pa ìdáhùn rẹ àkọ́kọ́ rẹ́ pátápátá kí o tó kun àlàfo tó bá ìdáhùn rẹ tuntun mu. Wo èyí fún àpẹẹrẹ.*

Èwo ni kò bá ìlànà àkọtọ́ Yorùbá mu?

A. Ìrètí
B. Ta ni
C. Yóò sùn
D. Ńbọ̀

*Ìdáhùn sí ìbéèrè yìí ni* Ńbọ̀*, nítorí náà, olùṣèdánwò yóò kun àlàfo* D *nínú ìwé ìdáhùn rẹ̀.*

[A] [B] [C] [D]

*Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.*

## ÌPÍN A – ÈDÈ
## ÀKÀYÉ

*Ka àyọkà ìsàlẹ̀ yìí, kí o sì dáhùn ìbéèrè tí ó tẹ̀lé e.*

Lẹ́yìn ọdún mẹ́rin tí Àṣàkẹ́ délé ọkọ ni wàhálà bẹ̀rẹ̀. Ohun tó sì fà á kò ju àìtètèrọ́mọbí. Láwùjọ Yorùbá, bí kò bá sí ọmọ, ìfẹ́ ọ̀hún yóò ṣá láìpẹ́.

Lọ́jọ́ tí ìyá Àdìsá ti sọ̀rọ̀ sí ọmọ rẹ̀ ni wọ́n ti gba ìjàngbọ̀n lálejò nínú ilé wọn. Lẹ́yìn èyí, kò sí ohun tí Àṣàkẹ́ mọ̀ ọ́n ṣe mọ́ lójú onítirẹ̀. Ìgbà tí wàhálà fẹ́rẹ̀ẹ́ pin ín lẹ́mìí ni ó bá kó jáde. Lẹ́yìn oṣù mẹ́ta tí ó kó jáde ni Àjílé wọlé. Òun náà kò gbọ́ pá kò gbọ́ po.

1. Kí ni ìṣòro Àṣàkẹ́?
   A. Àìmọ-ìkẹ́-ọkọ ṣíṣe
   B. Àìrí-ọmọ-bí
   C. Àìrí-ilé-ọkọ gbé
   D. Àìlè-tọ́jú-ìyá-ọkọ

2. .............................. ni ó dá wàhálà sílẹ̀ láàárín tọkọtaya.
   A. Àjílé
   B. Ìkóbìnrinjọ
   C. Àìnísùúrù
   D. Ìyakọ


www.myschoolgist.com

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com


**3.** 'Onítirẹ̀' tọ́ka sí

A. Àjílé.

B. Ìyakọ.

C. Àdìsá.

D. Àlejò.

**4.** 'ìn' tí a fàlà sí nídìí tọ́ka sí

A. ìyakọ.

B. Àjílé.

C. Àdìsá.

D. Àṣàkẹ́.

**5.** Àyọkà yìí fihàn pé pàtàkì ìgbéyàwó ni

A. ìtọ́jú ọkọ.

B. ìfẹ́ ọkọ.

C. ọmọ bíbí.

D. ìtọ́jú ilé.

Dáramọ́lá wòye pé ó yẹ kí òun àti àwọn àbúrò òun yẹ́ bàbá àwọn sí fún iṣẹ́ takuntakun tí ó ṣe lórí wọn. Bí ó sì ti jẹ́ pé ó ku oṣù mélòó kan kí ó pé àádọ́rin ọdún, wọ́n fẹnu kò láti ṣe ayẹyẹ ọjọ́-ìbí fún un. Láìfi àsìkò ṣòfò, Délé pinnu láti ra màlúù, Akin fọwọ́ sọ̀yà láti pèsè ọtí àti oríṣìíríṣìí ohun mímu yòókù nígbà tí Ṣadé gbà láti bójú tó aṣọ tí ọlọ́jọ́-ìbí àti ìyàwó rẹ̀ yóò wọ̀. Lọ́jọ́ ayẹyẹ, tijó tìlù tìfọn ni ọlọ́jọ́-ìbí, ọ̀rẹ́ àti àwọn ènìyàn fi ṣe ayẹyẹ. Ó fi ẹ̀mí ìmoore rẹ̀ hàn fún ẹ̀yẹ ńlánlà tí wọ́n ṣe fún un.

**6.** Ta ni wọ́n fẹ́ ṣe ayẹyẹ fún?

A. Délé

B. Apèsè-ọtí

C. Dáramọ́lá

D. Ọlọ́jọ́-ìbí

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com


7. Àwọn ọmọ ṣe ayẹyẹ fún bàbá wọn nítorí

A. ó ti di arúgbó.

B. ẹ̀mí ìmoore tí ó fi hàn.

C. iṣẹ́ takuntakun tí ó ṣe.

D. ọmọ púpọ̀ tí ó bí.

8. 'Ó' tí a fàlà sí nídìí tọ́ka sí

A. bàbá.

B. ìyàwó.

C. àkọ́bí.

D. ọ̀rẹ́.

9. 'fẹnu kò' túmọ̀ sí

A. dábàá.

B. pinnu.

C. tiraka.

D. ṣèlérí.

10. Àkọlé tí ó bá àyọkà yìí mu jù ni

A. iṣẹ́ takuntakun.

B. pípé ààdọ́rin ọdún.

C. fífi ẹ̀mí ìmoore hàn.

D. Dáramọ́lá ṣe bẹbẹ.

## ÀRÒKỌ/LẸ́TÀ

11. "Alágbàtà ń sọ ọjà dọ̀wọ́n" jẹ́ orí-ọ̀rọ̀ fún àròkọ

A. aṣàríyànjiyàn.

B. aṣàpèjúwe.

C. asọ̀tàn.

D. ajẹmọ́-ìṣípayá.

www.myschoolgist.com

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com


12. Bí o bá kọ ìwé sí àjọ atúnlùútò, irú àròkọ tí o kọ ni

A. ajẹmọ́-ìṣípayá.

B. ìsọ̀rọ̀gbèsì.

C. aṣàpèjúwe.

D. onílẹ́tà.

13. Èwo ni ó jẹmọ́ àròkọ aṣàpèjúwe?

A. Ayọ̀ níí pànìyàn

B. Iṣẹ́ ni oògùn ìṣẹ́

C. Ilésanmí dùn joyè lọ

D. Ààfin ọba ìlú mi.

14. "Iṣẹ́ akadá ṣòro" jẹmọ́ àròkọ

A. aṣàpèjúwe.

B. aṣàríyànjiyàn.

C. ajẹmọ́-ìṣípayá.

D. asọ̀tàn.

ÈTÒ ÌRÓ

15. Àfẹ̀gbẹ́-ẹnu-pè ni

A. [ r ].

B. [ l ].

C. [ w ].

D. [ f ].

16. [ h ] jẹ́

A. àfitán-án-nápè.

B. àfàjàpè.

C. àfèrìgìpè.

D. àfàfàsépè.

www.myschoolgist.com

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com


17. Ọnà ìṣẹnupè ni

A. àfèji-ètè-pè.

B. àfèrìgìpè.

C. àsénupè.

D. àfeyínfètèpè.

18. [ a ] jẹ́ fáwẹ̀lì

A. òkè.

B. odò.

C. ẹ̀bákè.

D. ẹ̀bádò.

19. Fáwẹ̀lì roboto ni

A. [ i ].

B. [ u ].

C. [ a ].

D. [ e ].

20. Ìhun sílébù 'àgbébọ̀' ni

A. fk-kf-kf.

B. f-kfk.

C. f-kf-kf.

D. fk-f-kf.

www.myschoolgist.com

## GÍRÁMÀ

21. Ọ̀rọ̀-orúkọ aṣeékà ni

A. yanrìn.

B. omi.

C. ẹsẹ̀.

D. àgbàrá.

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com

22. "Inú ń bí mi, mo ń bínú" ni àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀-ìṣe

A. aṣokùnfà.

B. alápèpadà.

C. asolùwàdàbọ̀.

D. àsínpọ̀.

23. "Mo lọ sí ilé kíákíá", 'kíákíá' jẹ́

A. ọ̀rọ̀-àpọ́nlé.

B. ọ̀rọ̀-ìṣe.

C. ọ̀rọ̀-atọ́kùn.

D. ọ̀rọ̀-àpèjúwe.

24. "Aṣọ Olú ti ya", 'Olú' jẹ́ ẹ̀yán

A. ajórúkọ.

B. aṣàfihàn.

C. aṣàpèjúwe.

D. aṣòǹkà.

25. Nínú "èmi yóò lọ", 'yóò' jẹ́ atọ́ka

A. àsìkò ọjọ́-iwájú.

B. àsìkò afànámónìí.

C. ibá-iṣẹ̀lẹ̀ àṣetán.

D. ibá-iṣẹ̀lẹ̀ bárakú.

26. "Ire wà nínú ibi" jẹ́ àpẹẹrẹ gbólóhùn

A. àṣẹ.

B. ìbéèrè.

C. alátẹnumọ́.

D. àlàyé.

www.myschoolgist.com

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com

## ÌTUMỌ̀ ÈDÈ

*Túmọ̀ ọ̀kọ̀ọ̀kan gbólóhùn wọ̀nyí sí èdè Yorùbá.*

**27.** He sings while working.

A. Ó máa ń kọrin bí ó bá ń ṣiṣẹ́.

B. Ó máa ń kọrin níbi iṣẹ́ rẹ̀.

C. Ó máa ń ṣiṣẹ́ bí ó bá ń kọrin.

D. Ó máa ń ṣiṣẹ́ níbi tí ó ti ń kọrin.

**28.** He has been elevated.

A. Ó ti di ènìyàn gíga.

B. A ti gbé e ga.

C. Ó ti gboyè àgbà.

D. A ti mókè.

**29.** The committee was reminded to be punctual.

A. A rán ìgbìmọ̀ náà létí láti wá.

B. A rán ìgbìmọ̀ náà létí láti tún wá.

C. A rán ìgbìmọ̀ náà létí láti tètè dé.

D. A rán ìgbìmọ̀ náà létí láti dé.

**30.** The driver lost control of the vehicle.

A. Awakọ̀ náà ṣì ọkọ̀ wà.

B. Awakọ̀ kò lè darí ọkọ̀ náà mọ́.

C. Awakọ̀ náà sá eré àsápajúdé.

D. Awakọ̀ náà kò mọ ọwọ́ ọkọ̀ náà.

www.myschoolgist.com

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com

## ÌPÍN B — LÍTÍRÉṢỌ̀

*Dáhùn* **gbogbo ìbéèrè** *tí ó wà ní ìpín yìí.*

ỌGBỌ́N ÌTỌPINPIN LÍTÍRÉṢỌ̀

**31.** .............................. ni a fi máa ń ṣàdá bí ọ̀rọ̀ bá fẹ́ yíwọ́.

A. Wọ́rọ́kọ́
B. Wọ̀rọ̀kọ̀
C. Pẹlẹbẹ
D. Gbọọrọ

**32.** Èwo ni àwọn àgbà sọ pé ilẹ̀ dídà máa ń pa?

A. Iyèkan
B. Ọ̀rẹ́
C. Olè
D. Ẹrú

**33.** "A ń wírú, o ń wírù" jẹ́ àpẹẹrẹ

A. àsọrégèé.
B. ìfohùndárà.
C. àfiwé.
D. ìfirósínròójẹ.

**34.** "Ilé Akin gba gbogbo ayé" jẹ́ àpẹẹrẹ

A. ìfohùngbohùn.
B. àwítúnwí.
C. ìfohunpènìyàn.
D. àsọrégèé.

www.myschoolgist.com

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com


LÍTÍRÉṢỌ̀ ÀTẸNUDẸ́NU

ÌTÀN ÀRÒSỌ

ÒJÓ, O: *Ìjàpá Tìrókò Ọkọ Yánníbo.*

Nínú ìtàn ***Ìjàpá àti Àwọn Ẹranko***

35. ........................ ni wọ́n fi jẹ alága ìpàdé àwọn ẹranko.

A. Erin
B. Kìnìún
C. Ẹkùn
D. Ehoro

36. Iṣẹ́ tí wọ́n fún Ehoro ṣe ni láti

A. pọn omi.
B. kéde ìpàdé.
C. rí alága.
D. bẹ Baálẹ̀.

37. Báwo ni wọ́n ṣe ri omi?

A. Òjò tí ó rọ̀
B. Wọ́n rúbọ
C. Wọ́n gbẹ́ ilẹ̀
D. Wọ́n kọ orin

www.myschoolgist.com

EWÌ ÀBÁLÁYÉ

ABÍMBỌ́LÁ, W.: *Àwọn Ojú Odù Mẹ́rẹ̀ẹ̀rìndínlógún (p1 – 51)*

Nínú "***Odù Èjì Ogbè***"

38. ...................... ló bímọ méjì.

A. Ọba
B. Ààyá
C. Ẹyẹlé
D. Eégún

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com

39. Kí ni a sọ pé ó ń polè?

A. Èpè

B. Alájọbí

C. Orò

D. Ẹkùn

40. Ẹyẹlé ló

A. ṣorò ikú lórí itì ọ̀gẹ̀dẹ̀.

B. sanwó fóníṣègùn.

C. dáko àgbàdo.

D. gbẹbọ lọ́wọ́ Ọ̀ṣun.

ERÉ ONÍṢE

ÒGÚNNÍRAN, L.: *Eégún Aláré*

41. Ta la fi jẹ baálẹ̀ Arẹ̀kú-eégún?

A. Dáṣọfúnjó

B. Lárinnàká

C. Ọ̀jẹ́làdé

D. Dúdúyẹmí

42. Dúdúyẹmí ló

A. bá bàbá rẹ̀ lọ sájò.

B. fẹ́ Àńséétù

C. dọ̀bálẹ̀ fún Ọ̀jẹ́làdé.

D. tọ́jú Ìyádùnní.

43. ..................... ló di màlúù.

A. Àmọ̀ọ́

B. Dúdúyẹmí

C. Ọ̀jẹ́làdé

D. Dáṣọfúnjó

www.myschoolgist.com

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com

## LÍTÍRÉṢỌ̀ ÀPILẸ̀KỌ

## ÌTÀN ÀRÒSỌ

ÒNÍ, K.: *Ojú Rí.*

**44.** Báwo ni Kọ́ńkọ́ọ̀dù ṣe jẹ́ sí Ògúngbèmí?

A. Ọmọ

B. Ọmọọmọ

C. Bàbá àgbà

D. Ẹ̀gbọ́n

**45.** Ògúngbèmí lọ sí Máradán nítorí

A. aṣẹ́wó.

B. owó.

C. ọtí.

D. kàríkà.

**46.** Róòsì ni

A. Kọ́ńkọ́ọ̀dù bá pàdé níbi ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò.

B. ó mú Kọ́ńkọ́ọ̀dù lọ kàwé ní ọ́ọ́fíìsì.

C. Kọ́ńkọ́ọ̀dù gbé níyàwó.

D. ó mú Kọ́ńkọ́ọ̀dù lọ wòran ní gbọ̀ngàn Odùduwà.

www.myschoolgist.com

## EWÌ ÀPILẸ̀KỌ

ADÉBỌ̀WÁLÉ, O.: *Ìgbà Lonígbàá Kà*

Nínú ewì ***Ajígbọ́toge***

**47.** Owó tó yẹ kí bàbá fi pilẹ̀ ọlà ni ó fi

A. gbàwòsàn l'Árò.

B. ra bọ́ńfò.

C. foge mọ́ra.

D. wo èèdì.

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com



Nínú ewì ***Ẹ̀gúnjẹ***

**48.** Èwo ni ìtumọ̀ rẹ̀ yàtọ̀ si 'ẹ̀gúnjẹ'?

A. Rìbá

B. Owó ẹ̀yìn

C. Obì

D. Ẹ̀wù àgbékọ́

**49.** Kókó-ọ̀rọ̀ inú ewì yìí ni

A. ẹ̀gúnjẹ ti wà tipẹ́.

B. ọ̀pọ̀ ènìyàn ló ń gbẹ̀gúnjẹ.

C. ìṣípayá lórí ẹ̀gúnjẹ.

D. ẹ̀gúnjẹ yóò jà bí ẹ̀pé.

ERÉ ONÍTÀN

ẸṢỌ́-OLÚBỌRỌ̀DÉ, S.: *Ìyàwó Aláréde̍*

**50.** Ta ló yarí pé Mojèrè kò gbọdọ̀ fẹ́ Ọládélé?

A. Atẹ́rẹ́

B. Túndé

C. Àyìndé

D. Kọ́láwọlé

**51.** "Tó bá jẹ́ èmi, màá ya á jẹ ní tútù".

Ta ló sọ ọ̀rọ̀ yìí?

A. Mojèrè

B. Àdùkẹ́

C. Àṣàkẹ́

D. Fúnmi

www.myschoolgist.com

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com


**52.** "Wòkè kí o wolẹ̀, iná mọ́ ọ"

'Iná mọ́ ọ' túmọ̀ sí

A. ojú tì ọ́.

B. ọrùn wọ̀ ọ́.

C. orí rẹ̀ bàjẹ́.

D. ọwọ́ tẹ̀ ọ́.

ÌPÍN D — ÀṢÀ

Dáhùn **gbogbo ìbéèrè** tí ó wà nínú ìpín yìí.

**53.** Òrìṣà wo ni à ń pè ní 'Olóde'?

A. Ògún

B. Ṣàngó

C. Ṣànpọ̀nná

D. Egúngún

**54.** 'Tùre' jẹyọ nínú àṣà

A. ìgbéyàwó.

B. ilà kíkọ.

C. irun dídì.

D. ìsìnkú.

**55.** Èwo ni orúkọ tí à ń fún àbíkú?

A. Ìdòwú

B. Kílàńkó

C. Àjàyí

D. Ọdẹ́rìndé

www.myschoolgist.com

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com


56. ........................ ni a fi ń se gbẹ̀gìrì.

A. Àgbàdo
B. Erèé
C. Ọ̀gẹ̀dẹ̀
D. Ìrẹsì

57. Ẹni tó ń fi eégún mọ̀nà ni à ń pè ní

A. atọ́kùn.
B. amúṣàn-án.
C. àgan.
D. ọlẹ́gùn.

58. Èwo ló jẹmọ́ iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ?

A. Ọṣọ́
B. Apáṣá
C. Ẹwìrì
D. Afàkò

59. Èwo ló tóbi jù nínú àwọn wọ̀nyí?

A. Gbárìyẹ̀
B. Ṣapará
C. Ọ̀yàlà
D. Dàńdógó

60. "Àrẹdú o" là ń kí

A. akọ̀pẹ.
B. aláró.
C. onídìrí.
D. oníṣọ̀nà.

www.myschoolgist.com